**Lakaye Ọrọ**

Ṣugbọn iwọ, nigbati iwọ ba ngbawẹ, fi ororo kun ori rẹ, ki o si bọju rẹ. Ki iwọ ki o maṣe farahan fun enia pe, iwọ ngbawẹ, bikoṣe fun Baba rẹ ti mbẹ ni ikọkọ; Baba rẹ ti o si riran ni ikọkọ yio san an fun ọ ni gbangba (Matteu 6: 14-18).



# Irohin Yoruba

NO. 823. MARCH 15 — MARCH 21, 1961 KOBO MEJI (2D)







# ADEBỌWALE DI ASẸYIN

**AWỌN ara Isẹyin fi Ọmọ-Ọba Raji Adebọwale jẹ Ọba Asẹyin Isẹyin ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi. Ọba Alaiyeluwa Bello Gbadegẹshin Ladigbolu Keji, Alafin Ọyọ, si ti ni ọwọ sii, ati Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pẹlu.**

Inu gbogbo awọn ara Isẹyin ni o si dun fun oye Asẹyin titun na ti nwọn jẹ, nitoripe gbogbo awọn ara ilu na ni o parapọ ba a yọ ayọ ifinijoye na.

Ninu awọn alabaṣẹyẹ ti o ko ilu wa ibẹ ni Oloye Bashọrun Isẹyin, Ikọlaba, Ojon, Ose, Ẹkẹrin, Ẹkarun, Balẹ Koso, Balẹ Isalu, Papin (Ọba Imale) ati Iyalode Ilu ati awọn enia pataki-pataki miran.

Nigbati Ọmọ-Ọba Adebọwale nlọ jẹ oye na, ẹṣin ni o gun lọ, nwọn si tun fa ẹṣin kan dani tẹle e, ti nwọn pa fi ṣe etutu ni ọhun, ki nwọn to jawe oye le e lori. Lẹhin ti nwọn jẹ ẹ tan ni Oloye na lọ si ibi ile Etutu kan ni Igbo lẹba Ebẹdi. Nibẹ ni yio gbe fun ọsẹ meji ki o to pada wa si Afin rẹ.

Ki a de pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ o.



Aworan oke yi ni ti Ọba Asẹyin titun. Gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ Isẹyin, Ọba na wa ni ile etutu nisisiyi, yio si lo ọsẹ meji nibẹ ki o to wa si Afin rẹ.

## Akano jẹ oye Bashọrun Ọyọ

ỌYỌ.

LẸHIN ti Ọba Alaiyeluwa Bello Gbadegẹshin Ladigbolu Keji, Alafin Ọyọ ti fi ọwọ si i pe Ọgbẹni Esuọla Akano ni Bashọrun Ọyọ tọ si, ti gbogbo awọn Ọyọmisi si ti lowọ si i, ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba fi aṣẹ si i pe Esuọla Akano ni Bashọrun Ọyọ.

Awọn Oloye Afọbajẹ Ọyọ si fi Ọgbẹni Esuọla Akano na jẹ oye Bashọrun Ọyọ ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi. Bashọrun titun na si ba gbogbo awọn ara ilu sọrọ pe on yio lo aye Bashọrun na ni ọna ti yio tẹ gbogbo ilu Ọyọ ati agbegbe rẹ lọrun nipa iranlọwọ Ọlọrun.

Inu gbogbo awọn enia, Ọyọ si dun si Oloye na, nwọn si bẹrẹ si i jo, ti nwọn nyọ ni ile Oloye titun na ati yika gbogbo ilu Ọyọ titi ti ilẹ ọjọ na fi ṣu.



Bashọrun Ọyọ Titun

## Oyewusi sọ ọrọ

IBADAN.

NIGBATI aṣoju iwe irohin wa lọ si ọdọ Alhaji Oyewusi ti on pẹlu Akano ti jijọ ndu oye na, ohun ti Oyewusi sọ nipa fifi Akano jẹ oye Bashọrun Ọyọ nipe, iyalẹnu ni o jẹ fun on, nitoripe on ni ẹtọ si oye Bashọrun Ọyo ju Akano lo.

Nigbati aṣoju wa bi i lere pe kini o ha fẹ ṣe si nisisiyi, o ni on ko le ti i sọ on ti on le ṣe si i na, afi bi ọkan on ba balẹ. Ọpọlọpọ awọn enia ni o si nwọ wa sibẹ wa a tu u ninu.

## Awọn Imale Eko ko f'ohun ṣọkan

**NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ati ọjọ Aje ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Apapọ Ijọba Naijiria ya si ọtọ fun ọjọ isinmi ọdun Itunu-awẹ.**

Nigbati a bẹrẹsi ṣe iwadi lọwọ awọn agba Imale Eko bi gbogbo Ijọ Musulumi Eko ba panupọ lati kirun ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi tabi nwọn ko pa ẹnu pọ, esi ti olukuluku nwọn fun wa niyi:—

Lemọmu-Agba Ijọ Ilu. Liadi Ibrahim sọ pe ni ọjọ Aiku ti iṣe kọkandinlogun ni awọn Ijọ ti ilu yio kirun. Lemọmu-Agba na sọ fun wa pe on ti gbọ kakiri pe awọn kan ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun ni awọn yio kirun, o ni gẹgẹbi eto ẹsin Islam, ki iṣe ọjọ Aiku ni ọjọ ikirun, bikoṣe ọjọ Abamẹta.

Alhadji A. Kesington, Oloye Balogun gbogbo Ijọ Alalukurani l'Eko sọ pe ọjọ Abamẹta ni ọjọ ikirun. O ni ọjọ na ni gbogbo apapọ igbimọ Musulumi ni Naijirai ti fi ẹnu si, o ni ko to dipe awọn ṣe ifohunṣọkan nipa ọjọ Abamẹta yi, awọn ṣe ipade pẹlu awọn ikọ lati Abẹokuta, Ibadan, ati ọpọlọpọ ilu miran ni Najiria, pẹlu awọn ijọ Gambari ati awọn miran. O ni ninu ipade ti awọn ṣe l'Eko ni awọn ti ṣe ipinnu pe ọjọ Abamẹta ni awọn yio kirun, o ni o ya ọpọlọpọ awọn olori ijọ Musulumi l'Eko lẹnu lati tungbọ pe adehun ti awọn ti ṣe pẹlu awọn ara ilu miran ni Naijiria ti tun yipada lẹhin igbati awọn ti sọ fun Ijọba nipa ipinnu awọn na, ti Ijọba si ti ṣe ikede rẹ.

Iyawo Lemọmu - Agba awọn Ijọ Ahmadiya, Iyaafin Nusiratu Tijani, sọ pe ọjọ Abameta ni awọn Ijọ ọkọ on Alhaji Ashafa Tijani, yio kirun.

Ọkan ninu olori Ijọ Ansar-Ud-Deen, sọ fun wa pe ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun ni awọn yio kirun. Awọn Ijọ Zumuratul Islamiyya paapa si ti ṣe ikede pe lọjọ na ni awọn yio kirun.

Ṣugbọn Alhadji S. A. T. Awẹlẹnjẹ, Olori Igbimọ Apapọ Musulumi Naijiria sọ fun wa pe laisi ani-ani, ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ọjọ ikirun ọdun, gẹgẹbi eto ẹsin Islam. O ni ko gbọdọ si atako si ọjọ ti Lemọmu-Agba, Liadi Ibrahim l'Eko ti pe ni ọjọ ọdun, o si rọ gbogbo awọn Musulumi pe ki nwọn ṣe ara wọn lọkan o ni ninu iṣọkan ni anfani ajẹẹjẹtan wa.

**ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN**

# ALUBARIKA L'OJU (8)

**OLOTU Iwe "Irohin Yoruba" ẹ nlẹ bẹun loni o? Gẹgẹbi asọti ọrọ wa, bayi ni gbogbo enia nwọ bi omi ninu ile "IBUKUN-OLUWA-LO-JU" ti on pẹlu iya ọmọ-tuntun na si ngnawo bi ẹlẹda titi ti o fi di ọjọ ikomojade.**

Inawo si tun nlọ bakanna lẹhin nkan bi oṣu marun ti nwọn ti bi ọmọ na, nwọn si pe oruko ọmọ na ni "MOFOLORUNSO."

Bayi si ni gbogbo nkan na si tubọ ntẹsiwaju fun awọn obi ọmọ na ni ojojumọ aiye, ọmọ na si ndagba diẹdiẹ. Lẹhinti "MOFỌLỌRUNṢỌ" ti dagba to ọmọ ọdun marun ni iya rẹ to loyun le e, ṣugbọn nigbati iya na yio bimo, ibeji ni o bi, awọn ibeji mejeji si jẹ ọkunrin bakanna.

### LAITẸ, LAIWỌ

Laifa ọrọ gun lọ titi mo, bakanna si tun ni ẹnu ko le gba irohin nipa inawo akoko na, to bẹ ẹ ti gbogbo awọn ara ilu fi nsọ wipe awọn ko ri iru inawo ti o to bayi ri ni ilu yi.

Lẹhin ti nwọn pari gbogbo inawo yi tan ni nkan bi ọdun kan abọ, gbogbo nkan na si nlọ deede bakanna, laitẹ, laiwọ.

Nigbati o di owurọ ọjọ kan bayi, ni "IBUKUN-OLUWA-LOJU" ba sọ fun iyawo rẹ pe, ara on fẹ-ẹfa diẹ. Ere ni, awada ni, lẹhin ọjọ diẹ, "IBUKUN-OLUWA-LOJU" ṣe akiyesi wipe, aarẹ na si nfẹ yatọ si gẹgẹbi on ti npe e.

O si kesi iyawo rẹ pẹlu awọn ọmọ keekeeke ti o jẹ ọmọ rẹ, o ṣe ikilọ fun won wipe, "pẹlẹpẹlẹ di ọwọ nyin o," nitoripe aarẹ yi nda on laamu pupọ o. Atipe, ẹnikẹni ko si le mọ ibiti nkan na le yori si ṣugbọn pataki nkan ti on fẹ sọ fu nwọn ni wipe "bayowu ki nkankan ti le to laiye, ẹ ko gbọdọ fi enu nyinṣe epe-kepe lailai."

### IBUKUN JALAISI

"Atipe, nṣe ni ki ẹ si ṣọra lati pa ẹnu nyin mọ nitoripe bi ọrọ ti mo sọ fun nyin yi ba lẹ re e han si ita gbangba, nkan na yio kokọ buru na bi o tilẹ jẹ wipe igbẹhin rẹ yio dun. Nitorina bi ohun kohun ba pa ẹnyin pẹlu ẹnikẹni pọ, ẹ ko gbodo sepe o.'

Bayi ni Ogboni yi pari ọrọ rẹ ti nwọn si mba nkan na bọ bakanna, ṣugbọn lẹhin oṣu mẹta lori aisan yi, "Ibukun-Oluwa-LO-JU" jalaisi, okiki si kan yika gbogbo ilu, ọran wa di "bi o ko lọ, ki o yago fun mi." Gbogbo ilu bẹrẹ si rọ gilagila, to bẹ ẹ ti ẹnikan ko le duro de ẹnikeji.

Bayi ni "Ibukun Oluwa-Loju" ṣe fi aiye silẹ, ti gbogbo aimọye dukia yi si wa nibẹ fun iyawo rẹ pelu awọn ọmọ rẹ keekeke mẹtẹta.

Gbogbo awọn ẹbi "Ibukun Oluwa Loju" ati awọn ẹbi iyawo rẹ si bẹrẹsi nawo fun ti isinku na, to bẹ ẹ ti gbogbo awọn ara ilu fi bẹrẹsi yin won fun ti inawo na, bi o tilẹ jẹ wipe, "owo awe na ni nwọn fi ngwọn awe lori."

Bayi ni nwọn ṣe titi ti nwọn fi pari isinku na lẹhin nkan bi oṣu mẹta.

### ASỌTẸLẸ FARAHAN

Lẹhin igbati rogbodiyan inawo isinku "IBUKUN-OLUWA-LO-JU" rọlẹ tan bayi ni asọtẹlẹ ọrọ rẹ bẹrẹsi farahan. Gẹgẹbi owe awọn Yoruba kan ti o sọ wipe, "Bi a ti nyọ ọ wi, ni a nyọ ọ gbọ," bi ilẹ ti mọ gbara ni owurọ ọjọ kan bayi, bẹni awọn enia mẹta kan wọle de, ti nwọn si ki iyawo "IBUKUN-OLUWA-LO-JU" yi daradara, ti nwọn si ba a kẹdun iku ọkọ rẹ na.

Lẹhin ti iyawo yi ti ṣe wọn lalejo rẹpẹtẹ tan, ni awọn alejo mẹtẹta na ba kesi iyawo na wipe, "ẹ ṣeun pupọ, ẹ si ku inawo, Ọlọrun yio forijin oku na o".

Lẹhin eyi, nwọn bere lọwọ iyawo na pe, "njẹ ẹ mọ wa baun bi?" iyawo na si sọ fun wọn wipe, "Ẹ dakun nko mọ nyin!" Nwọn si tun dahun wipe, "Njẹ ọkọ nyin sọ fun nyin rara nipa nkan ti o wa ni arin awa pẹlu rẹ baun?" Iyawo na si dahun pe, rara o!"

### AWỌN ALEJO

Awọn alejo mẹtẹta na si wo ara wọn loju, nwọn mi ori wọn titi pẹlu iyanu, nwọn nṣe, "ha! ha!! ha!!! Aṣe, Ibukun-Oluwa-loju" le fi aduru ọrọ nla bayi pamọ fun iyawo rẹ titi ti o fi ku? O ma ṣe o!"

Nwọn si tun bere lọwọ iyawo na wipe "Ẹyini ni wipe ọkọ nyin ko sọ fun nyin nipa ẹgbẹrun pọnun ti a wa gbe pamọ si i lọwọ ni nkan bi oṣu mẹfa sẹhin? Ha! Igi ma da o!!"

Iyawo na si yara da wọn lohun pe, rara o, ọkọ on ko gba ohunkohun pamọ lọwọ ẹnikẹni. Lori eyi ni awọn alejo mẹtẹta na ba bẹrẹsi ṣẹ epe nlanla, nwọn si sọ fun iyawo na pe ki on na wa ṣepe.

Bayi ni ọrọ ba fi di "wo mi, nwo o," iyawo na ko si le ṣepe gẹgẹbi ikilọ ti ọkọ rẹ ti ṣe fun un nigbati o wa laiye. Nigbati ariwo nla bẹrẹsi ta, ti awọn alejo mẹtẹta na bẹrẹsi ṣẹ epe ni ọkan-ko-jọ-kan pẹlu ohun igbe rara, ti ọrọ na ko si ni ojutu mọ, ni iyawo na ba sinu iyara, o si gbe ẹgbẹrun pọnun fun awọn ọkunrin na, nwọn si ba ọna ti nwọn lọ.

Olotu, a o tun ma a fi rere pade o, Ọmọ-ọba nrele o, o digba.

**(KOI TI PARI)**





**Ki ọpa-ẹhìn le tọ-rọrọ ki tapa-titan si lagbara dada FUN ỌMỌ RẸ NI**

# OSTERMILK

**Ile iṣẹ egbogi Glaxo Laboratories Ltd., Greenford, England ni ọ ...ṣe e**

Awọn alagbata rẹ ni GLAXO-ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P.M.B. 2310. Lagos ati pẹlu ni ABA ati KANO

# ITAN OŞUPA (9)

*(Lati ọwọ S. L. Ogunniran Ibadan)*

NIGBATI ọgbẹni yi pari ọrọ rẹ, Oşupa sọ fun un pe, on ko le tori owo tabi ipo ti enia wa di aya rẹ, nitori ọpọlọpọ ikoro ni o wa ninu adun ti a nwo lode ara, bẹni ko si ẹniti o le mọ pe inu rẹ jẹ ibajẹ. Apanijẹ ikoko a ma a bọ sinu awọ aguntan, on a si ma a şe bi ọrẹ otitọ şugbọn nigbati o ba sunmọni tan, a sọ aşọni di ẹran.

"EGBE NI FUN OLOJU KOKORO OBIRIN, TI O RI ODE AGO, ŞUGBỌN TI KO RI INU RẸ, TI O SI PẸ ODE AGO NA NI ADUN."

"Ah! Mo wi fun ọ, obirin na ti bọ si ikẹkun ibanujẹ; dajudaju yio si fi ika abamọ sẹnu lẹhin ọla. Okelegbigbẹ ati alafia san ju ile ti o kun fun ẹtan abọpa ati ibanujẹ lọ. Oşupa ni on ko le titori owo fẹ olowo nitori igba ni owo, o ni on ko le titori oşi kọ talaka silẹ nitoripe igba ni ailọrọ, nitori ọba to sọ olowo di talaka ni ọdun yi, le sọ talaka ọdun yi di olowo ọla.

### APO IPARUN

Ni ipari ọrọ rẹ, Oşupa sọ fun ọgbẹni na pe o dun on pe, ọgbẹni na ko ti i na owo rẹ na si ọna ti o ti le so eso rere fun un atipe, inu apo iparun ni o na owo na si, niwọn igbati o lẹ pe, olowo ati ọlọrọ enia bi tirẹ ni o na owo na fun. Oşupa sọ fun un pe, "awọn ti ara wọn le ko wa onişegun bikoşe awon ti ara wọn ko da.

"Nitorina, talaka ati alaini ni iwọ ki ba na owo rẹ yi fun, iwọ yio si gba iyi ati ẹyẹ ju eyi ti olowo ẹgbẹ rẹ le fun ọ atipe, Ọlọrun Ọba paapa nyọnu si awọn ti o nran talaka ati alaini lọwọ. On a si ma a bukun fun wọn.

"NINU ỌRỌ RẸ, IWỌ SỌ PE, IWO KORIRA AWỌN TALAKA, JỌWỌ MAŞAI MU IRU IWA BAYI KURO NI ỌKAN RẸ NITORI OLỌRUN KAN NI O DA GBOGBO WA.

Awọn talaka jẹ ẹda wọnni ti Ọlọrun ti şẹda wọn tan, oniruru enia ni o si mbẹ ninu wọn. Ọlọrun da wọn ni enia pataki si ori ilẹ, awọn ni o npa ofin Rẹ mọ. On na si fẹran wọn gidigidi. Bi ko ba si tagiri, awọ ko le hu, bakanna si ni bi ko ba si talaka ko si olowo. Agbara talaka ni olowo si fi nri igbega. Enia ti o ba tẹ lọwọ talaka, o tẹ lọwọ ẹlẹda. Olowo ti talaka ba buku, ko le ri abukun Ọlọrun Ọba. Nitorina, mo fẹ ki o pada lọ, ki o si na owo rẹ fun awọn talaka ati alaini, lẹhin eyi, bi o ba di ọjọ meje ki o wa ri mi.

### ỌLỌGBỌN WỌLE

Nigbati Oşupa pari ọrọ rẹ tan, OLORIOLOWO-AIYE bọsita o si lọ. O fẹrẹ ma ti to işẹju mẹta tan ti ọgbẹni ỌLỌGBỌNTIO-GBỌNJUAGBỌNLỌ fi wọle. Oşupa bere lọwọ rẹ bi o ba mu ohun ti on bere lọwọ rẹ wa. Ọgbẹni yi dahun pe, on mu u wa. Lẹhin na ni o fi aşọ kekere kan bayi han Oşupa, şugbọn omi ti o di sinu aşọ na ti jo danu ki o to de ile Oşupa.

Nigbati Oşupa yẹ ẹ wo, o bere lọwọ Ọlọgbọntiogbọnjuagbọnlọ pe, "kinişe ti ko si omi ninu koko aşọ na?" Ọgbẹni yi si dahun pe, "Ko si ọgbọn ti nko da si ọran yi tan, nko si simi lati ọjọ ti mo ti kuro ninu ile rẹ nitori ọran yi, ọgbọn ti mo si ri da ko ju eyiti mo mu wa siwaju rẹ yi lọ. Nitorina, mo fi Ọlọrun bẹ ọ, maşai da mi ni are ninu hilahilo mi."

Nigbati Ọgbẹni Ọlọgbọntiogbọnjuagbọnlọ pari ọrọ rẹ, Oşupa rẹrin musẹ, o si sọ bayi, "ohun nla ni o kọ oruko rẹ yi so, ẹnu si ya mi nigbati mo gbọ oruko na, idahun rẹ si ibere mi na si pa mi lẹrin jọjọ. Nitotọ, ko si ọlọgbọn ti o le ta omi ni koko si eti aşọ, bẹni ki yio si ẹni na ti yio le şe e titi aiye. Nitori ọjọ ti ẹlẹda ba fi aşiri ọgbọn han ọmọ araiye ni ile aiye yio di rudurudu.

"Nitorina, mo gbọ ọrọ rẹ, anu rẹ tilẹ şe mi fun gbogbo wahala rẹ. Bi o tilẹ jẹ pe o şe igberaga si ẹlẹda nipa oruko rẹ, o ti ronupiwada bayi o si ti kọ ogbon titun, nitorina ma a lọ sile rẹ loni yi, bi o ba si di iwoyi ọjọ meje, jẹ ki nri ọ".

### IYẸPẸ ETI OKUN

Bi Ọgbẹni Ọlọgbọntiogbọnjuagbọnlọ ti njade kuro ninu ile Osupa ni Ọgbẹni Ọmọrantiojuopẹlẹ wọle de, Oşupa si ba eleyi ni na sọrọ dada. Nigbati Oşupa bere iye yanrin eti okun ati ti erupẹ ilẹ, Ọgbẹni Ọmọrantiojuopẹlẹ ni, on ko tilẹ le ka ẹkunwo kan ninu yẹpẹ ti o wa lori ilẹ, benie eyi ti o wa leti okun. O ni nitorina on rọ osupa ki o fẹ on nitori Ọlọrun Ọba. O ni Edumare ko ni gbe idanwo ti o ju u lọ ko o loju.

Ni idahun si ọrọ yi, Oşupa sọ pe "nitotọ, bi ọlọgbọn kan ko ti lẹ ta omi ni ikoko si eti aşọ bẹ na ni ko si ọmọran ti o le sọ iye yẹpẹ ilẹ. Ogboju babalawo kan ko tẹ ara rẹ ni ifa ri, ani, baba ọmọran kan ko le fi ara rẹ joye, şugbọn awọn ọmọ araiye ko mọ eyi, igberaga si ti sọ wọn di enia yẹpẹrẹ. Nitorina, mo gbọ ohun ti o wi, ngo si fun ọ ni esi rẹ ni iwoyi ọjọ meje, maşalai de ọdọ mi."

O fẹrẹ ma to işẹju marun ti Ọgbẹni na lọ tan ni Ọgbẹni Enia-Abiwatutubiosun wọle de. Nigbati Ọgbẹni na joko, Oşupa bere lọwọ rẹ pe, "şe ko si nkan o? Şe bi oşu mẹta ni mo sọ fun ọ pe ki o gbe larin awọn enia na ki o to wa si ile mi, ọjọ na ha ti pe bi?"

### EBUTE OFO

Nigbati Ọgbẹni Enia-Abiwatutubiosun gbọ ibere Oşupa yi, o ta ika sori rẹ o si wipe, "Ọlọrun majẹ ki ngbe oşu kan larin awọn enia bẹ ẹ, nitori ọjọ ti emi pẹlu wọn kọ sun pọ ninu ile ni ọran wọn ti sumi, ọjọ kẹta ti mo si de ibẹ ni emi pẹlu wọn ti fi ija pẹẹta, afi igbati mo salọ kuro ni ọdọ wọn ni ọjọ kẹrin ni mo

(Wo oju ewe kesan)





# Ọba Sikiru Adetọna Awujalẹ Ijẹbu-Ode gba iyi l'Eko

Ọjọ nla ni ọjọ Eti ti i ṣe ọjọ kẹta oṣu yi fun gbogbo awọn ọmọ Ijẹbu to wa nilu Eko, paapa fun gbogbo awọn Egbẹ Ọmọ Oduduwa nigbati Ọba Alaiyeluwa, Sikiru Adetọna, Ogbagba keji, Awujalẹ Ijẹbu Ode wa bẹ ilu Eko na wo. Eyi ni akọkọ wa Ọba na lati igbati o ti gun ori oye. Eyẹ ati iyi ọjọ na si ga pupọ.





# ITAN OṢUPA

AGBARA IFẸ

ỌNA META

(KO TI PARI)



## Ọmọ ile iwe ku iku iyanu

IBADAN.




O KURO NINU ERE-IJE ?

Taji loju oorun Ki o si ṣ'ara giri !

Pẹlu

ANDREWS LIVER SALT

LARO, LOSAN TABI LALẸ . . . MU

ANDREWS

LIVER SALT

FUN FIFỌ INU . . . . FUN OKUN ARA

Surf ni AGBARA IDAN -lati jẹki aṣọ mo dada!







SURF ni irọrun ti o dara ju lọ fun fifọ aṣọ mọ dada !




# ITAN KONGO (3)

(Lati ọwọ T. Ajayi Thomas, Eko)

LARIN oşu kini si ekeji ọdun ti o kọja yi (Jan.-Feb. 1960) ni pataki-pataki ninu awọn Oyinbo ara Belgium ti nwọn wa ni ilẹ Kongo gba ara wọn jọ, ti nwọn si lọ şe ipade pataki kan ni ilu Brussel ti işe Olu-ilu Belgium lati jiroro lori eto a ti fun awọn ara ilẹ Kongo ni Ominira Ijọba wọn.

Şugbọn nitoripe nwọn ko le da ipade yi şe laisi awọn ọmọ-Ibilẹ Ilu Kongo pataki-pataki ninu ipade na ni nwọn ba fi ranşẹ lọ mu Patrice Lumumba jade wa lati ile ẹwọn ti nwọn ju u si, o si pẹlu wọn şe ipade na.

**IJIRORO LORI OMINIRA**

Nigbati ipade Ijọba Brussel yi bẹrẹsi şe ijiroro lori ọrọ na, nwọn ri i ka ninu ofin Ijọba Ilẹ Brussel pe ẹtọ ni ki nwọn fun awọn ara ilẹ Kongo ni Ominira Ijọba wọn ni ọjọ karun oşu keji ọdun ti o kọja yi (5-2-60).

Şugbọn asẹhinwa-asẹhinbọ, nwọn şe ileri pe, awọn yio fun awọn ara ilẹ Kongo ni Ominira Ijọba wọn ni ọgbọnjọ oşu kẹfa ọdun na (30-6-60).

Lẹhinna ni nwọn wa sọ fun awọn enia ilẹ Kongo ti o wa ninu ipade na pe ki nwọn lọ se idibo gbogbo-gboo lati fi yan ẹnikan fun Alakoso Ijọba ilẹ wọn na

**LUMUBA BORI**

Nigbati nwọn pari ipade nla yi, awọn ara ile Kongo pada si ilu wọn lati bẹrẹ ipalẹmọ fun idibo gbogbo-gboo na. Awọn Aşoju Igbimọ mọkanleladoje (131) ti o wa fun Ile Igbimọ Ilu Kongo (Members of the Kongo Parliament) ni nwon nilati dibo fun.

Nigbati nwọn si pari idibo na ninu oşu karun ọdun 1960, Patrice Lumumba ni o gba aye ijoko ti o pọ ju ti ẹnikẹni lọ ninu awọn Aşoju ti nwọn dibo fun wọle Igbimọ na.

Bayi si ni aye ijoko ti nwọn gba ninu idibo na:—

Patrice Lumumba gba aye ijoko mẹtadilogoji (37) Kasavubu gba ogun (20) Antoine Cizenga gba ogun (20), Tshombe gba mewa (10) awọn aşoju miran gba ibo mẹta (3), meje (7), mefa (6) ati bẹ ẹ bẹ ẹ lo.

Nigbati abayori idibo na je wipe Lumumba nikan ni o gba aye ijoko ti o pọju ni nwon ba kesi pe ki o se eto lati ko Ijọba na jọ. O si ro ọrọ na wo fun odidi ọjọ marun ki o to fesi wipe, on ko le ko Ijọba jọ pelu awọn aşoju mẹtadilogoji (37) pere nigbati o jẹ wipe enia mọkanleladoje ni o nilati wa ni Ile Igbimọ.



Aworan yi ni ti igbati nwọn mu ologbe Lumumba pe o ko owo awọn onişowo jẹ ati wipe o nda ilu ru ni ọdun 1957 ko pẹ lẹhin eyi, wọn da a ni ide nitoripe wọn ko le şe apejọ ilu Brussel lai jẹ pe o wa nibẹ, nitori on ni ilu nfẹ.

**NKRUMAH DASI I**

Nwọn tun pe Kasavubu, on na tun ro o fun ọjọ mẹrin, şugbọn ko le şe e. Bẹ ẹ si ni Kasavubu nfẹ jẹ Alakoso Ijọba, Lumumba na si nfẹ jẹ ẹ pẹlu.

Nigbati o di wipe, ẹnikẹni ninu wọn ko ni enia to lati ko Ijọba na jọ ki o si şe Alakoso rẹ ni Ọgbẹni Kwame Nkrumah Alakoso Ijọba ilẹ Ghana ti işe ọrẹ Ologbe Lumumba timọtimọ ba fi imọran ranşe si Lumumba.

Imọran ni pe ki o ba Kasavubu, Antoine Gizenga, Tshombe ati awọn yoku ti nwọn jijọ dibo fun won dapọ gẹgẹbi ara kan, ki nwọn si di akojọ Ijọba kan. Lumumba gba imọran yi, o si ba won dapọ.

Nigbati awọn aşiwaju Ijọba ilẹ Kongo wọnyi darapọ ti nwọn ko Ijọba na jọ tan, Lumumba yan ipo Alakoso Ijọba (Premier) fun ara rẹ, o yan Kasavubu si ipo Olori-ilu (President), o yan Anthony Kasanga si ipo 'Gbakeji Alakoso Ijọba (Vice-Premier).

**IGBA OMINIRA**

Nigbati nwọn şe eto na bayi tan, ko tẹ Kasavubu lọrun rara nitoripe ipo Alakoso Ijọba gan an ni o fẹ ki nwọn yan on si.

Lẹhin gbogbo eto wọnyi ni nwon ba tẹ ikede Ijọba wọn jade ni ọjọ kini oşu kefa ọdun 1960 pe awon yio gba Ominira Ijoba awọn ni ọgbọnjọ oşu na (30-6-60).

Nigbati o si di ọgbọnjọ oşu kẹfa ọdun 1960 ti nwọn fi ọjọ gbigba Ominira Ijọba Kongo na si ni Ọba Boudouin ti Brussel ba wa si ilu "Belgian Congo" funra ara rẹ lati fun wọn ni Ominira Ijọba na.
Ipade ajọyọ Ominira na bẹrẹ ni deede agogo mẹwa owurọ ọjọ na. Ọba na si ba awọn ara ilẹ Kongo sọ ọpọlọpọ ọrọ, lẹhin ti Ọba na sọ ọrọ tan ni Lumumba ba dide lati fesi si ọrọ na.

**ESI ỌRỌ LUMUMBA**

Esi ti Ọgbẹni Patrice Lumumba fi si ọrọ Boudouine Ọba Brussel na gbona gidigidi, o si sọrọ de aye ibi ipakupa ti awọn Oyinbo ara Belgium pa awọn ara ilu Kongo ninu ọdun 1930 nigbati a wọn enia na fi aake-kọri pe awọn ko ni şişẹ fun wọn ninu oko ireke ati oko ọgẹdẹ mọ.

O si sọ nigbangba ijoko na pe, awọn enia ara ilẹ Kongo ti awọn Oyinbo ara Belgium pa ni ipakupa danu ni ọjọ na jẹ ọkẹ marun le ẹgbaarun (100,000) enia.

Lumumba fi ibinu ati igbonara sọrọ pupọ ni ọjọ na, o si fi ọpọlọpọ ninu ọrọ rẹ lu koro mọ Ọba Boudoine paapa lara.

Nitori ti awọn enia Ilẹ Kongo ti nwọn pa yi Lumumba fi ọrọ gun Ọba na lara de aye ti o fi pari ọrọ rẹ si ibi wipe, inu awọn ko fi bẹ ẹ dun si Ominira Ijọba ti Ọba na fun awọn yi, nitoripe bi awọn ba ti ranti awon ti nwọn pa danu na ni inu awọn tun mbajẹ.

**INU BI ỌBA**

Esi gbigbona yi mu ki Ọba nla yi binu, ọkan rẹ si rẹwesi.Ọba yi nikan kọ ni o binu, Kasavubu paapa binu kọja aala, nigbati Lumumba nsọrọ ibinu na lọwọ ni Kasavubu gbe dide nibiti o joko si, o si sọ fun un pe ki o dakẹ ni o si dakẹ ọrọ sisọ.

Nigbati o di ọjọ keji ti nwọn pari ọrọ na Kasavubu lọ pa Ọba Boudouine lẹhin ninu ile rẹ ni ọjọ keji oşu kẹfa ọdun 1960, o tọrọ aforijin lọwọ rẹ nipa ọrọ ibinu ti Lumumba sọ si i lara.

Ọba na si fi ọwọ wọnu, o darijin Kasavubu, şugbọn o ni Lumumba sinu gidigidi. Nwọn si bẹrẹsi ba işẹ eto Ijọba na lọ.

(KOI TI PARI)



